# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ A/YE, TẸNI GBOGBO LAWA

No 767 TUESDAY AUGUST 11 1964 (2D)


## Ọkunrin kan Fẹ pa Ara Rẹ Nitori Obinrin kan Soso

IDI-ORO Ni ọjọ Abamẹta ti tṣe ọjọ kẹjọ oṣu yi ni ọkunrin kan ẹni ọdun mejilelọgbọn jabọ lati ori oke pẹtẹsi ni nọmba *11* Akala Street Idi-oro lẹba Eko lori ija kan to ṣẹlẹ larin ọkunrin na ati iyawo rẹ ni ọsan ọjẹ na.

Ọkunrin ọdaran yi si ni ariyanjiyan lori ọrọ kan pẹlu iyawo rẹ eyiti o fi jẹ ija fi ṣẹlẹ larin awọn tọkọ taya na eyiti gbogbo a w ọ n aladugbo wọn si pe le awọn mejeji lori Nigbati awon aladugbo won bere oro lowo ọkunrin na atiiyawo rẹ ti gbogbo wọn rojọ ni nwọn ba Pari ija na larin awọn tọkọ ta'iya na lati le jẹjọ wa ni irẹpọ laiko si edeaiyede mọ.

Sugbọn nigbati nwọn pari ija na tan ni ọkọ obinriu na ba mura tio si silo sidi iṣẹ rẹ, Gẹgẹbi irohin ti nwọn fi ye oinwe irohin wa pe lẹsẹkẹsẹ ti ọkọ obinrin na si fi ile silẹ ni iyawo pa pal gbogbo ẹru rẹ mo ti o si salọ.

Awọn aiadugbo na tun fi ye oniwei rohin wa pe nigbati ọkunrin na de ti ko ri iyawo rẹ ti o wo gbogbo ile tio mọ fo lo b a bẹ lati oju ferese tio bẹ silẹ lati pa ara rẹ oniwe irohin wa fi ye wa pe okunrin na ko ku sugbọn nwọu tete kesi awọn ọlọpa lati mu lọ, Awọn aladugbo na ko sọ oruko ọknnrin na fun oniwe irohin wa.

# ẸGBẸ AFẸNIFẸRE ATI ALAKUKỌ FẸ DI ẸGBẸ OṢELU KAN

ABA:- Ẹgbẹ Afẹnıfẹre ati ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ti nṣe eto gegebi egbẹ mejeji na yio ti se le di ẹgbẹ oselu kan ṣoṣo ni orilẹ ede Naij·ria, irohin na de ọwọ wa latı ọwọ onirohin wa ni Aba' oniwe irohin tun fi ye wa pe irohin na de owọ on lati ibi ipa le kan ti Dokita S. A Aluko ọkan ninu awọn igbimọ ọmọ ẹgbẹ Afẹnıfẹre ati olukọ ni ile ẹkọ Unifasity ti Ifẹ tẹlẹ fi ọrọ na nye ipade ẹgbẹ ọdọ ti ẹgbẹ Afẹnifẹre eyiti Dokita Aluko lọ ba awọn ẹgbẹ ọdọ na sọrọ nı Aba ni Ipinlẹ Ila-Orun Nigeria laipẹ yi.



**Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ**
Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

Ninu ọrọ ti Dokita S A. Aluko ba awọn ọdọ ẹgbẹ Afẹnıfẹre sọ ni pe o jẹ chun to tọ ati eyı to yẹ lati le tete gbero gẹgẹbi awọn ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Alakukọ yio ṣe papọ gẹgẹbi nwọn yio ṣe jẹ ẹgbẹ oṣelu kanna ati pe idi tin wọn ni lati fi papọ ni fun eto ofin rere, alafia ati Ijọba rere fun Orilẹ ede Naijiria. Dokita Aluko tun ṣe alaye fun awọn ẹgbẹ ọdọ Afẹnifẹre pe ti ẹgbẹ Afẹnifẹre ati ẹgbẹ Alakukọ ba papo di ẹgbẹ oṣelu kanna lo le mu irọrun wa fun ilẹ Naijiria.

Siwaju si Dokita Aluko tun sọ fun awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre jakejado ipinlẹ Ila Orun Naijiria pe ajumọsepọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ati ẹgbẹ Alakukọ lo jẹ pataki bayi. Dokita Aluko tun fi ye awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre pe tı awọn ẹgbẹ mejejı na ba wa ni ajumọsepọ pe ko ni si pe ẹgbẹ kan nfi iya jẹ ẹgbẹ keji lori eto ọrọ oselu ni jakejado ipinlẹ Ila Orun Naijiria.

Ninu ọrọ ti Dokita S. A. Aluko tun fi ye awọn ọmọ ẹgbẹ ọdọ Afenıfẹre ni pe o dabi ni pe igba kanna ni nwọn tu Ile Igbimọ asofin ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria ati ile ıgbimọ asofin ti apapọ Ijọba Ile Najıria ka.

Dokita Aluko fi han gbangba pe eyikeyı ti nwọn ba tete tuka ni awọn ile Igbimo asofun mejeji pe ẹgbẹ Afẹnifẹre si ti ṣe tan lati ba ẹgbẹ Alakukọ ṣe pọ ati pe ki iṣe pe ẹru lo nba awọn ọmọ ẹgbẹ wọn rara. Dokita Aluko tun fi ye awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre pe awọn ti mura silẹ nigbakugba ti nwọn ba tu ile Igbimọ aṣofin ti Ijọba apapọ tabi ti Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ni awọn ọmọ ẹgbẹ wọn fi ti mura silẹ ati pe nwọn yio si bori ibo na.

Dokita S. A. Aluko tun fi ye awọn ọmọ ẹgbẹ Afenifere pe ẹgbẹ Olomi N. P. C. to irinwo ọkẹ ponun (£8,000,000) jọ lati fi ṣe eto ipolowo ibo si ile igbimọ asofin ti apapo ile Naijiria ati si ile igbimọ asofin ti Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.



**Dokita M. I. Okpara**
Olori Ẹgbẹ Alakukọ

Ninu ipade kan ti, Alakoso eto Aje fun apapo Ijoba ileNaijiria MallamWaziri Ibrahim ba awọn oniwe irohin sẹni ilu Aba ninu ipari ọsẹ to kọja ni Mallam Waziri Ibrahim ti sọpe ẹgbẹ on N. P. C ti ṣe gbogbo eto tan fun imura silẹ idibo si ile igbimọ aṣofin tiapapọ Ijọba ile Naijiria atipe ẹgbẹ on si fi se eto lati ran ẹgbẹ Dẹmọ N N D lọwọlati le bori ibo si ile igbimọ aṣofin ti Ijọba ipinlẹ Iwọ orun Naijiria Mallam Waziri Ibrahim tun fi ye awọn oni Irohin pe o da on loju pe ẹgbẹ on N P C ati awọn alabaṣepọ rẹ yio bori ibo si ile igbimọ aṣofin ti apapọ ijọba ilẹ Naijiria ati papa fun gbogbo dibo ti nwọn bale ṣe ni ilẹ Naijiria

Mallam Waziri Ibrahim tun fi ye awọn oni Irohin pe o da on loju p ẹgbẹ on N P C ni lati bori ibo mejeji ni ilẹ Naijiria Mallam Ibrahim sọ pe ko si gẹgẹbi o le ṣe ri pe awọn si ti ṣe eto to yẹ ati eyi totọ lati ri pe ẹgbẹ N P C yio bori ibo na.

Mallam Waziri Ibrahim tun ṣe alaye fun awọn oniwe irohin pe bo tilẹ jẹ pe awọn ẹgbẹ wọn ko le ṣe akoso ilẹ Naijiria, Mallam Waziri Ibrahim sọ pe awọn ni lati bo i ibo si ile Igbimọ Aṣofin Apapọ Ijọba ilẹ Naijiria ati awọn Alaba ṣe pọ ẹgbẹ wọn.

# Ọtẹlẹmuyẹ Eko

Ẹ ku lailai, ẹku atijọ mẹta, oju ti o ri nyin ma gbo o. mo ki gbogbo onkawe Irohin Imọlẹ lọkunrin, lobinrin, lọmọde ati Oyunnu pe ẹ ku ọjọ mẹta.

Ojojumọ ni mo nri "Letters" nyin gba ni ilu mi ajiran pe, ṣe alafia ni mo wa ṣe ara mi le tabi ka le, ẹwa ti ṣe ti awọn kọ fi gburo mi mọ; a bi ogun un ni o si jẹki nfala ṣoko ni? mo ka "letter" titi oju mi sokun oyi kọ mi, mo digbo lulẹ gbirigidi lati ori bẹdi sọfa mi, mo si ṣe ni ibadi ọpẹlọpẹ "FASILINI" ti mo ti mo fi ntọju Igbaroka mi Ki a ma fa ọrọ gun ẹnyin ti ẹ nkọwe si mi, ẹ k aniyan ẹ ku ifẹ, ẹ ku lailai, Oluwa ko ranti nyin si rere, nko ku, bẹni nko si run, nko si farasoko.

Nko mọ ohun ti o nlọ lode mọ, ni ọsẹ yi ni ngo tun bẹ sita gẹgẹbi iṣẹ mi bi Odua ko ba si kọ iṣẹ ẹni rẹ, ẹo tun ma ka chun ti mo ba ri, ninu Irohin Imọlẹ yẹn bẹ, emi Ọtẹlẹmuye atokoro wọnu ado fi eyi kede fun awọn ọkawe Irohin Imọlẹ pe ẹnikẹni ti o ba fẹ fe igbeyawo t bi ti o ba fẹ joye ni ilu ni, tabi ni mọṣalaṣi, ki okọwe si emi Ọtẹlẹmuyẹ bi Ọlọrun fẹ Irohin ati Photo ohun ti Oluwa rẹ ba ṣe yio jade tan patapata ninu irohin Imọlẹ, aiye yio gbọ, orun paapa yio mọ.

Ẹnikẹni ti o ba fẹ, pemi si ibi ariya ki o kọwe si Ọtẹlẹmuyẹ iwe Irohin Imọlẹ 16 Bamigbose Street Lagos ngo s ri ba ko si ilu ti nko lede o

# Yẹ Irawọ Rẹ Wo

AQUARIUS (Jan. 21-Feb 19) Ẹnikẹni ti o jẹ ẹniti o fẹran yio fẹ lati mu o binu, nṣe ni ki o ṣe suru fun iru ẹni bẹ, iwọ pẹlu rẹ yio si bere si de deedee si ara nyin bi ọre.

PISCES (Feb. 20-March 20) Iṣẹ yio wa nilẹ fun ọ lati ṣe lọpọlọpọ, eyiti o kọkọ ti wa nilẹ laiṣe ni ki o kọkọ yanju na.

ARIES (March 21-April 20) Aisedede yio wa ninu iṣẹ rẹ l ni, ṣugbọn iwọ pelu ọrẹ rẹ yio ba ara yiu sọrọ aladuu kan ni alẹ oni.

TAURUS (April 21-May 22) I ọ yio ri ọna owo ṣe ju ti atẹhin wa lọ, bi o ba ti mọ iṣẹ na to nigbadun yio fi wa fun ọ ninu owo na.

GEMINI May23-June21:- Ọrẹ rẹ kan to jẹ ẹniti o mọ aworan ni yiya ni ọrọ kan lati ba ọ sọ, faaji ati igbadun yio pọ fun ọ.

CANCER (June 22 July 22) Ọpọ aniyan ti o ti da lati ṣe ohun kan yio kuna, sugbọn eyi o ko gbero lelori ni yio ba ẹhin yọ si ọ

Leo July 23- Aug 22 O le ri ọpọlọpọ iranlọ gba iati fi ẹnikan mọna nipa ṣiṣile rẹ.

Virgo Aug 23 Sept Awọn obirin ni yio jẹ oluranlọwọ fun ọ nipa iṣẹ rẹ ọpọlọpọ iṣẹ ni iwo yio pari kiakia.

Libra Sept 23 -Oct 23-gbogbo nkan ti o ba fẹ ṣe o ye kio ṣe ni kiakia. iteri iwọ yio ni asiko lati sun won siwaju bi o ti fẹ.

Scorpio Oct Nov 22 Owa yio tẹ ọ lọwọ jaburata ọbadun ti iwọ yio jẹ lalẹ oni k ri ẹgbẹ ni.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec. 21:-) Maṣe wo tabi ki maṣe taro ohun ti ẹnikan ṣe si o ni aidara, Fi ọkan balẹ lori wọn iwọ yio ri nkan iyanu kan lalẹ oni ti ọjọ ṣe oni anfani.

CAPRICORN (Dec 22-Jan 20:-) Ayipada diẹ yio de si ọ ninu iṣẹ rẹ ṣe iṣẹ na daradara bi o ba ti nlọ, eyi ni iyi rẹ.


# EGBOGI JEDIJEDI

BERE EGBOGI



"CYCLOVEN"

Aworan ẹgbẹyi fihan gban gba ibiti Jẹdijẹdi rẹ ba wa lara rẹ si nyọ ọ lẹnu nigba gbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu tabi iho idi enia biiti a ma be ṣe igbọnṣẹ Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buro ni pataki fun ọkunrin ti o si lagbara pupọ la i ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri ode nisisiyi ti won ma a polowo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya la leri mẹwa ninu awọn egun ni o le ṣe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe bọyi bi wọn ba lọ si ile lati lọ ke eyiti oba nyọ jade lati omusu ku nipa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Ṣugbọn awa ko ro bẹ rara lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bẹrẹ bakana Orisirisi Jẹdijẹdi ni o wa, Ekini ti o bẹrẹ nipa aiko ma ṣe igbọṣẹ dede tabi lojojumọ ẹlomiran nipa ijako ni ojukanna pupọ ojojumọ tabi tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ẹwẹ fẹran Ṣuga oniruru ohun adidun pupọ, pupọju nigba kugba Jẹdijẹdi di orisirisi ni o wa, ewo ni tiaẹ? Bi o nyọ jade ninu omuṣu tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnṣẹ tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbọnṣẹ tan ni tabi ti nrin ọ ninu omuṣu ni eyikeyi ti o ba jẹ bere egbogi CYCLOVEN ti awọn Oyinbo Jamani ṣẹṣẹ wa ldi rẹ kio si danwo risi i mẹ a daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹdi patapata alfia lo de ọ ekeji rẹ ko si ninu gbogbo egbogi atata nigboro Nijiria kejoda bere ni:

NIGERIAN MEDICNE STORES
4, Tinubu Square Lagos
Adedun Chemist
14, Workeman Street, Yaba

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street, Lagos
Phone:- 2287 Naigeria, (Ọja Ita Faji)



B O BA NI

# Iwe—Titẹ

FUN

**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orișirișí Iwe itufọ tabi ijade Oku**

ATI

**Iwe Igbeyaw**

KỌWE SI ILE—IṢẸ—ẸRỌ ITẸ IWE

**Modupẹ Printing Press**
16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.

KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO POOKU NI A SI NGBA

IROHIN KO TO AFOJUBA
Dan wa wo lẹkan ṣoṣo ko si ri iyato

# IWE SI OLOTU

## A Nfę Irohin Imǫlę Ni Ilu Akoko

Olotu, Iba dun mǫ mi pupǫ bi ę ba le şe eto gegę bi Iwe Iro-Imǫlę yio ti şe le de Ilu Akoko ni ori gbogbo awǫn Agbagba ti o mǫ Iwe Yoruba ka ni o ngbadun Iwe na gegębi oti şe njade şugbǫn ai ko ri Iwe na deede ko ję ki agbadun rę dada

Nitorina a bę Olotu Iwe Irohin Imǫlę lati boju to eleyi fun wa, awa ǫdǫ papa ngbadun Iwe na nitori o tun ję ohun iyi fun awa ǫmǫ Yoruba lati ma ka iwe Irohin lede Ilę wa nipa bę a bę Olotu pęlu awǫn Isǫngbe rę lati boju to eyi fun wa, a o ma reti nyin o Olotu.

Mo dupę aye ti ęgba mi Olotu Iwaju ni ę o ma lǫ,

Emi ni,
F. A. Ǫladele
OMUO—AKOKO.

## Ęfi Ǫkan Olu-Ikarę Balę

Olotu

Ędakun ęgbami laye dię ninu iwe nyin oloyin mǫmǫ ti njade ni ojojumǫ tio si nkǫ wa ni ǫgbǫn ati oye lati bę awǫn Ijǫba Iwǫ Orun ki wǫn fi Ǫkan Ǫba Amusa Momoh Olu Ikarę balę dada

Ǫpǫlǫpǫ ębę ni mo bę ęuyin Ijǫba Ipinlę Iwǫ Orun lati fi Ǫba yi silę nirori owo cşu ako nifę Idamu kankan fun Ǫba na nitori Ǫba Amusa kişe kǫja agbara rę kişe Ǫba Amusa nikan ni bi koşe gbogbo Ǫba ti owa ni Akoko

Nitori awǫn Ǫba Akoko kifi aşǫ wǫn kǫ sibi ti ǫwǫ koto Ǫwǫ wǫn kosi ninu Ijękuję rara wǫn mǫ Iwǫn ara wǫn Nitorina ęfi Ǫba Amusa silę pęlu enia rę gbogbo

Mo gbe oju soke mo si gbe oju mi si isalę mo wo gbogbo Ǫba ti o wa ni Ipinlę Iwǫ Orun O fę jępe gbogbo wǫn ni Ifę owo ti gba ǫkan wǫn ti wǫn ti wǫn ko si mǫ ara wǫn ni agba mǫ nitori i aiye atijǫ awǫn Ǫba ni Iyi ju asiko lǫ nitorina wǫn ko fi agba wǫn wǫlę to ti aiye Isisiyi Sibęsibę awǫn Ǫba ti owa ni Akoko si mǫ ara wǫn l'agba irufę Ijękuję bayi koi ti wǫ wǫn ni ęwu rara.

Iba dara pupǫ ti ęba le fun awon Ǫba ni ifayabalę pęlu aye ti olukuluku wǫn wa.

Mo dupę Olotu fun aye ti ę gba mi, agba ama jęyin da o

Emi ni
J. S: O, Aribiy
OMUO - AKOKO

## Ǫwa Ilesha Titun Nkǫ ?

Ęjǫwo Olotu *Irohin* Imǫlę inu mi yio dun pupǫ ti ę bale gba mi laye dię lati ba awǫn Afi Ǫbaję ibile Ilesha sǫrǫ lori ati ję Ǫba tuntan fun ilu Ilesha

Oti to odun kan bayi ti Ǫba Ilesha ti waja ti awǫn igbimǫ afi Ǫba ję Ilesha ko ti ri ęni ti wǫn yio fi ję Ǫba Ilesha eleyi dabi ęnipe ko si ęniti o gbǫn ti o si le yan Ǫba na ni, ni oju temi osi je itiju nla fun awa Ilesha lęhin ti Ǫba Ilesha ku ni Ǫba ilu Ibadan w ja ti nwǫn si ję Ǫba miran ejǫwo ęyin afi Ǫba ję Ilu Ilesha ę ba wa yan Ǫba miran ti yio se ilu wa ni anfani lǫpǫ yi o.

Emi ni
Abimbǫla Smith
Ilesha

## A Nfǫ Iwe Itan Ǫgbęni J. O. Şhǫyinka

OLOTU:- Inu mi yio dun bi ę bale gba mi ni aye dię ninu iwe Irohin Imǫlę nyin ti njade ni ojojumǫ, ti osi nkǫ wa ni ǫgbǫn ati Oye lati ba Alagba wa Ǫgbęni J. O. Shǫyinka sǫrǫ lori itan ti on fun wa yi Itan na dun pupǫ gbogbo wa ni angbadun rę.

Şugbǫn nkankan ni o ku latişe nkan na ni pe ki o mura ki osi gbaradi gęgębi aşaju rę Alagba D. O. Fagunwa ti oti nfun wa ni iwe itan aladun bayi iru Iyęn gan ni ohun ti o ku ti Ǫgbęni J. O. Shoyinka yio şe ti Itan rę ko ni fi parę ni ilę Yoruba.

Alagba wa, ęma tęsiwaju iwaju ni Ǫpa Ębiti nre si, ęǫ ni şeti Agba aję nyin da o ęo pę bi Ǫpę fun wa, Itan yi ko ni kǫ nyin lęnu lati ma sǫ (Amin),

Olotu mo dupę aye ti ę gba mi

Emi ni,
J. S. Bamishelę
EKO







OLUSHI SOCIL1STS

PRESENTS

FIRST ANNIVERSARY DANCE

at Foresters Centen..ry Hall

22, Odunlami Street Lagos

ON FRIDAY, 21st AUGUST, 1964, AT 6 p, m. till da

*MUSIC BY*

**New Time Enterprises Bashy & His Young Stars Orchestra**

Lad es and Gents, dont be t ld of h t happen at Foresters on that 21st August 1964, how Bashy will g ve you many latest hits a d h w New Time will give you many hits of Roy Ch cago, Eddie Okonta, I. K. Dairo & Broadway Dance Band Arom Ghana Bashy is asuring you to bri g along your Termogene or Mentholatum to rub your body after closing.

COME THERE IN TIME TO AVOID RUSHING

**Bar Bar Inexhaustible**

**Tickets 3s Flat**

Tickets obtainable at 16, B mgbose Street Lagos (Irohin Imole Office) and at 3, Olushi Street Lagos



MAFI OWO RĘ ŞE "OFO" MǪ NIPA RIRA AWǪN ǪBIRǪBI TǪNIKI NITORIPE OWO WǪN RǪJU ARA RĘ O NSE IYĘN DAJU O BĘRĘ OJǪLO AO H UNHAUN AYONRAN TǪNIKI TI WǪN NPE NI

## "MINOPHOS–TǪNIKI"

Aworan egbę yi fi han ǫ gbangba ti ęda eni ti ri la si "ĘRAN ARA" etipe ojulowo tǫniki to le şe işę ribiribi ni ęję ara, işǫri ara ninu egungun gegębi aworan yi to fi han ǫ, MINOPHOS Tǫniki a ma ęję fa titun si ara, papa ti e ia ba nru si ogurodo tabi fun wahala işę şişe aiko nri orun sun daradara to, beni o si darajulǫ pęlu bi ara enia ba n bcna nigba [illegible] tabi leh [illegible] bi [illegible] bi gb na b pǫ ju ǫ [illegible] igba [illegible].




At fun isǫ a tokun ati e [illegible] dabi enipe omurǫ tab [illegible] S [illegible] kan egbogi tǫniki yi [illegible] wǫ yio si ma [illegible] gbogbo enia pęlu. Bere ni Şǫ [illegible]:-

NIGERIAN MEDIC NE STORES
4 Tinubu Squ [illegible]

WATERLOO (CH P MED C [illegible] STORES
8, P LMCH CH S [illegible]
P, O, BOX 535

# Ogedengbe

## Apa Kini

Lati Qwọ BAYỌ TIAMIYU

Akọ ni Ogedengbe jẹ ninu awọn ologun ilẹ Yoruba ni igba satijọ. Fun dindi ogun tabi ọgbọn ọdun, ni Ogedengbe lọ ka kiri jakejado Ilẹ Yoruba, bi kiniun, lati ile to de ileto, ilu de ilu ati orilẹ ede de orilẹ ede ti o nsọ ilu nla di ahere ti o nsọ awọn ilu kekere di ahoro ti o npa enia bi ẹni pa ẹran ti o si nfi ẹjẹ awọn ti o şubu si ọwọ ibinu idi rẹ şe omi mu.

Ibaşepe awa ti a wa lori ilẹ loni wa laiye ni asiko ti Ogedengbe ni, awa iba mọ idi rẹ ti orukọ kanşoşo yi fi nmu ki awọn ọkunrin tọ si şokoto wọn, ki awọn obinrin şu si asọ wọn ti awọn ọmọde si ma sa di iya wọn mu nigbakugba ti nwọn ba gbọ ọ. Ọkanşoşo Ajanaku ti nmi ẹgberun igbo kijikiji ni Ogedengbe işe.

Bi o ti mi Ibadan ni o mi Ọyọ, bẹ ni o mi Ekiti Akoko, lyagba titi lọ si ilẹ Ibariba, Nupe ati awọn ilu miran ti o wa ni bebe odo Ọya.

Şugbọn bi o şe pe emi ati iwọ dede gbọ ariwo ilu ati ipe ogun bayi ki a jade si gbangba ki a si wa ri ọkunrin kukuru bi iku na ni ori ẹsin fuufun ti a fi ọmọlangidi he bi ẹnu ki a ri i pẹlu ẹwu ogun rẹ ti o fi ẹjẹ enia ati owo ẹyọ şe bi ọşọ, tabi ki a ri idi rẹ ti o fun fun bi ehin erin ti ndan bi aşẹşẹ yọ orun owurọ ti o şi nkọ bi manamana dajudaju a o fi ile, ọmọ, nyin, iyawo baba, ẹgbọn ati aburo wa silẹ a si fi ayọ idunnu ati itẹlọrun na jo tẹlẹ lẹhin lai bere ibiti o nlọ ati idi rẹ ti o fi nlọ. Bi o ba ro pe irọ mbẹ ninu ọrọ mi, nyo fi ye ọ pe baba ti o bi baba mi ati eyi ti o bi iwọ na pẹlu şe eyi ni iwọn adọrun ọdun sẹhin şugbọn nwọn ko ri ere kan gba nipa şişe bẹ.

Nwọn fi ile ati ohun gbogbo ti nwọn ni silẹ nwọn si tẹle Ogedegbe fun iparun ẹmi wọn. Bi o ba bere idi rẹ lọwọ mi, ko si ohun miran ti mo le sọ fun ọ ju wi pe ẹlere ni Ogedengbe işẹ gbogbo a begbe Iwọ Orun Naijiria ni oju agbo ere rẹ.

Ni gbogbo akoko ati igba lọsan, tabi loru ninu arun tabi ninu ojo, ko si ẹni ti o e gbọ pe Ogedengbe wa ni oju agbo ki o ma jade lati woran rẹ. O mọ iru orin ti yio kọ' o mọ ilu ti yio lu o si mọ iru ijo ti yio jo lati fi fa awọn enia mọra. Ebi ki pa awọn ti o ntẹle e lẹhin ongbẹn ki gbẹ wọn arẹ ki mu wọn bẹ si ni awọn ki ranti ile. Nitori kini? Nitori pe didun ilu nwọn daro le ọrọ ẹnu rẹ si ryọ wọn bi nje. Lẹhin iku rẹ papa kọ si ninu awọn ọmọ ogun Ogedengbe ti o ba a lọ si ogun. Iru enia bayi ni Ogedengbe ogboguugboro ọkunrin jẹ ni ọjọ wọnni şugbọn jọọ pẹ nisisiyi on papa ti ku p ti fi ilẹ bora awọn ọrọ nina rẹ si ti bi ọrọ itan.

Şugbọn nini idi re ti Ogedegbe fi di enia ela bẹ? ki ise pe agbara rẹ pọ ju ti awọn asaju ẹgbẹ rẹ, bẹ si ni ki şe pe oni ogun ju wọn lọ. Şugbọn igbo ya ifarada ainibẹru ati aişiye meji rẹ rekọja wọn. ko ni ẹni ti ko ro pe işẹgun awọn ara Ibadan lori Ijẹşa ni yio fi opin si agba ara Ogedengbe şugbọn bi ko ti bo gẹgẹbi ngo ti ladelẹ kedere.

Lẹhin ti awọn ara Ijeşa tẹriba fun agbara Ibadan, Ogedengbe fi ilu rẹ silẹ osi lo si Okere lati lọ dan agbara rẹ wo, Oko ba awọn ọmọ ogun-ogun ti o ku fun o si fi ori le lọna ilẹ Ekiti lati lọ pade awọn ara Ibadan nibẹ ni lo ti gbọ pe ohun ni wọn lọ. O gba ibẹ jade si Effọn nibiti oti ja fun oşu mẹta. Lẹhin eyi olọ si Aramọkọ pẹlu awọn ti o ko, lẹru ni Efton.

Nigbati Ogedengbe de Aramọkọ, o woye pe awọn ara ibẹ ko fẹ tẹriba fun agbara on, nitori eyi, o pinnu lati fi ajulọ han wọn. O paşẹ fun awọn ọmọ ogun rẹ lati duro ni ọna oko awọn Aramọkọ ko si jẹ ki awọn ara ilu lọ mu onjẹ ni oko.

On ati awọn ọmọ ogun rẹ bẹrẹ si ipa ẹnikẹni ninu awọn ara ilu ti ọwọ wọn batẹ ni ọna oko Nigbati ọrọ wa le patapata awọn ọkunrin bẹ rẹ si pa ara wọn ọmọ won ati iyawo nwọn

Ẹ o ma gbọ orin ti wọn kọ nigba miran.


MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING

*Firms Patronise* MODUPE PRESS

*Becuase Of Their;—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHOD PRINTING

*For Your Next Printing Jobs —*

Just Call 21985 - Leave the rest to Modupe

We Guarantee Neat Work And Quick Service

**Modupẹ Prnting Press**

**16 Bamgbose Street**

Phone 21985, Lagos



GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TONIKI



ALE-BI-ELE Egbogi Tọniki Jamọnu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ gbara ati Ajẹbidan işẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.

Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala lala şişẹşẹ ti o kọ ie jẹun daradara, tabi ki o male sun dada ọkun lọsan tabi loru tabi awọn işan ara rẹ gbogbo ki şe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradara wọn işẹ tabi wahala şişe tabi fun awọn ailera gbogbo 'nyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun o si de adọrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN' ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata anu rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bi ẹ s'i do dada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba y'Arẹ" ngbakugba yio salọ pẹlu igoaba-dun ati alafi diro de ọ. Iyẹn daju. Bere Egbogi na ni Şọbu: awọn

NIGERIAN- MEDICINE STORE
4, Tinubu Square Lagos

# IROHIN IMOLẸ

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 767. TUESDAY, AUGUST 11, 1964 (2D)


## Awọn Oṣiṣẹ Ile Iṣẹ Tiya Ti kọ Iwe Lati Da Iṣẹ Silẹ

IBADAN:- Ninu ipari ọsẹ to kọja ni a ọn Oṣiṣẹ ile iṣẹ ibi ti nwọn ti ṣe Taya ni Ibadan eyiti orukọ rẹ nje (The West African Tyre Retreading and Nito Company) ti iwe ida iṣẹ silẹ fun Alakoso ile na Alhaji Jimoh Odutọla eyiti awọn Oṣiṣẹ ile iṣẹ ra fun ni ọjọ mọkonlelogun pe ti nwọn ko ba ṣe eto lati fun wọn ni ni ẹkunwo owo-oṣu eyiti igbimọ oloyedi Morgan ṣe lati san fun awọn Oṣiṣẹ.

Awọn oṣiṣẹ na tun fi ye Alakoso ile iṣẹ na Alhaji Jimo Odutọla pe ti ko ba tele sẹ eto na ki ọjọ ti nwọn fun to pe awọn oṣiṣẹ na sọ pe awọn yio da iṣẹ silẹ Awọn igbimọ Oṣiṣẹ na fi ye oniwe irohin wa ni Ibadan pe lati gba ti nwọn ti fi iwe adehun eyiti Oloye Okotie-Eboh fi ranṣẹ si Alakoso ile iṣẹ na Alhaji Odutọla pe ki o fi ọmọ si lori eto ti awọn olori oṣiṣẹ awọn Asoju fun Ijọba ilẹ Naijiria ati awọn Asoju fun awọn ile iṣẹ gbogbo pe Alhaji Odutọla ko sọ pe on yio sẹ eto a ka loni oro na Awon igbimo ile awon oṣiṣẹ na so pe awon ki yio de iṣẹ silẹ ti ko ba tele d awọn l'ohun'

# BENSON NA IJỌBA IBILẸ IFẸ NI PASAN ỌRỌ

EKO:- Igbakeji olori ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Alakoso eto irohin ti Apapọ Ijọba ile Naijiria oloye T.O.S. Benson bu ẹnu ẹtẹ lu igbimọ Afunishọ ti ijọba ibilẹ Ifẹ ninu ọrọ ti awọn ọmọ ile igbimọ Afunishọ ti Ijọba ibilẹ Ifẹ na sọ ni ọjọ kejọ osu yi pe ki nwọn fun Ọba Adesọji Aderẹmi Ọni ti Ifẹ ni wakati mejidinladọta pe ki o fi ipo rẹ silẹ gẹgẹbi Ọba ilu Ifẹ.

Ni ọjọ Abamẹta ti iṣẹ ọjọ kejọ oṣu yi ni awọn Igbimọ Afunishọ ti Ijọba ibilẹ Ifẹ sọ pe ki ọba Adesọji Aderẹmi Ọni ti ilu ile Ifẹ tete fi awọn ohun to jẹmọ ti oko ti o ti wa lọwọ Ọba Ọni tẹlẹ pe ki o fi silẹ fun Ijọba ibilẹ ilu Ifẹ ati awọn owo ti Ọba Adesọji Aderẹmi ti ri ninu oko na lori igi Gẹdu pe ki o da gbogbo ow na pada fun Ijọba Ibilẹ ilu Ifẹ

Ninu ọrọ ti oloye Benson sọ lori ọrọ awọn ọmọ ile igbimọ na ni pe; gbogbo ọrọ ti awọn ọmọ Ile Igbimọ na sọ pe ko mu ọgbọn lọwọ ati pe ko si enia ti o ba jẹ enia rere ti yio gbọ ọrọ ti awọn igbimọ Afunshọ ti Ijọba Ibilẹ Ilu Ifẹ sọ ti yio sọ pe ọrọ kan ti enia to nilari ni lati ma gbe jade. Oloye Benson sọ pe gbogbo ọrọ ti igbimọ na sọ ni ko tọna rara.



Oloye Benson



Ọba Adesọji Aderẹmi
Ọni ti Ifẹ

Oloye Benson tun sọ ni-nu ọrọ rẹ pe ohun to jẹ pe awọn Igbimọ Afunishọ ti Ijọba Ibile ilu Ifẹ ni lati ṣe ni pe ki nwọn ro inu wọn jinlẹ ki nwọn to ma gbe ọrọ jade ati pe ki awọn igbimọ na ṣi lọ ṣora gidi ki nwọn ma tun fa ohun to le fa edeaiyede silẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ati pe ki nwọn tete mu ẹnu kuro lori ọrọ na ki eto ofin ati ilọsiwaju le wa ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Awọn ọmọ ile Igbimọ Afunishọ ti Ijọba Ibilẹ ilu Ifẹ tun ṣe alaye lori ọrọ wọn ki nwọn to sọ pe ki Ọba Aderẹmi fi ipo rẹ silẹ ni pe lati igbati nwọn ti pari ija larin Igbimọ Afunishọ ati Ijọba Ibilẹ ilu Ifẹ ati Ọba Aderẹmi pe ko ṣe nkankan nipa eto lori adehun ti awọn ba Ọba Adesọji ṣe lori ija ti nwọn pari ni ọjọ kẹta oṣu yi.

Gẹgẹbi ikilọ ti awọn igbimọ Afunishọ ti Ijọba Ibilẹ Ilu Ifẹ ṣe fun Ọba Adesọji Aderẹmi pe ki ofi ipo rẹ silẹ ti o ba mọ pe on koni mu adehun ti nwọn ṣe lasiko ija na ṣe yio pari loni yi ati pe ti Ọba Adesọji ba kuna gẹgẹbi ọrọ awọn igbimọ Afunishọ ti Ijọba Ibilẹ ilu Ifẹ osi daju pe Ọba Adesọji Aderẹmi yio fi ipo rẹ silẹ gẹgẹbi Ọba Ọni ti Ilu Ifẹ.

## Agbedemeji Ipinlẹ Iwọ Orun D'arugbo ọdun kan

BENIN:- Ni ana ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹwa Osu yi ni gbogbo awọn enia Agbedemeji Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria wa ni muku mukẹlẹ fun ajọyọ Ọdun kini ti Ipinlẹ na wa gẹgẹbi ipinlẹ ti o duro gedegbe fun ara rẹ ni orilẹ ede Naijiria gbogbo ilu Benin ti o jẹ ibu joko ijọba ipinlẹ lo kun fun ayo ni ọjọ na ati awọn ile iṣẹ Ijọba ipinlẹ na ni awọn osisẹ rẹ gba isinmi ni ọjọ na.

Ninu ọrọ ti Alakoso Ipinlẹ Agbedemeji Iwọ Orun Naijiria Oloye Dennis Osadebay si dupẹ gidigidi lọwọ awọn enia Ipinlẹ na fun itẹriba ti nwọn ni fun Ijọba Ipinlẹ.

Ninu awọn ọrọ ti Alakoso Ijọba Agbedemeji Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria tun sọ fun awọn enia Ipinlẹ na pe on dupẹ lọwọ awọn Ijọba. ati awọn osisẹ Ijọba ipinlẹ Agbedemeji Iwo Orun Naijiria fun ọdun kan ti ipinlẹ na duro gẹgẹbi fun ara rẹ ti o yori si rere ti ko si edeaiyede larin Ijọba ipinlẹ

Oloye Denins Osadesay tun gbadura pe to ba nje ogo Oluwa pe ko ni si aireju tabi airaye ni ipinlẹ na Oloye Osadesay tun gbadu ra pe airye ati airmu u ko ni ba awọn enia ipinlẹna

Ninu ọrẹ ti Alakoso Ipinlẹ Agbedemeji Iwọ Orun tun sọ fun awọn enia Ipinlẹ na ni pe on yio sa agbara on lati ri pe Ijọba on gbinyanju lati le mu itẹlọrun ba awọn enia ipinlẹ na ati lati le fun awọn ọmọ ipinlẹ na ni eto ẹkọ ọfẹ fun awọn ti wa ni ile ẹkọ giga ati lati le jẹ ki awọn ọna titun pẹlu awọn ọna o yẹ ki nwọn ṣe afara le lori ni gbogbo jakejado ipilẹ Agbedemeji Iwọ Orun Naijiria.

Oniwe irohin lati ilu Benin fi ye wa pe ọpọlọpọ iwe ikini ku orire ni o ti nde si ọwọ Alakoso Ijọba Agbẹdemeji Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria fun eto ẹyẹ ọdun kini ti ipinlẹ na da duro gedegbe fun rarẹ.


Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEỌSUN 45, Campbell Street Lagos 11/8/64.